# AṢIWERE ỌLỌ́RỌ̀

**Luku 12:1-34**

**ẸKỌ 44 --- FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: “Ki ohun ti ẹ ni ki o to nyin” (Heberu 13:5).**

### Gígùn Ayeraye

Jesu wa si ayé lati kọ́ eniyan bi o ṣe le gbé igbesi-ayé rere, ṣugbọn O tẹnu mọ ọn pe igbesi-ayé wọn nihin wà fun pipese wọn fun Ọrun. Lẹyin igba ti igbesi-ayé kukuru yii ba dopin, a o lo ayeraye nibi kan, yala pẹlu Oluwa ninu ogo, tabi pẹlu eṣu ninu iṣẹ oró. Awọn ti wọn kò ba mura silẹ lati pade Jesu ki i fẹ rò nipa ohun ti yoo ṣẹlẹ lẹyin ti wọn ba kú, ṣugbọn o daju pe wọn yoo gba ère iṣẹ wọn ti wọn ti ṣe kankan, gẹgẹ bi yoo ti ri fun awọn ti wọn ti mura silẹ.

Akoko ti o gùn pupọ ni ayeraye i ṣe, o gùn ju bi a ṣe le moye lọ. Yoo wà lae ati laelae lai si ibẹrẹ tabi opin. Gẹgẹ bi a ti wi pe kò si ẹni ti o dá Ọlọrun, ṣugbọn pe O wà nigba gbogbo, bẹẹ gẹẹ ni ayeraye – o ti wà laelae bẹẹ ni yoo si maa ri nigba gbogbo. “Gbogbo akoko ti o wà lati igba didá ayé, ati akoko ti a o pa ayé yii run, ki yoo to ọjọ kan ni ayeraye, ani iye ọjọ ti ó wà ninu ọdun pupọ wọnni ki yoo to wakati kan ni ayeraye.” Bawo ni o ti ṣe pataki to pe ki a mura silẹ lati pade Ọlọrun ni alaafia ki a má baa jiya oró ni ayeraye ti kò ni opin!

### Igbesi-Ayé Kukuru

Bawo ni ọjọ eniyan ninu ayé yii ti gùn tó? Dafidi wi pe “Ọjọ wa li aiye dabi ojiji” (1 Kronika 29:15). Ojiji a fara hàn ni iṣẹju kan, ni iṣẹju keji a si fò lọ. Bẹẹ gẹgẹ ni igbesi-ayé wa ninu ayé yii ri nigba ti a ba fi wé ayeraye. Jakọbu ni ero kan naa ninu ọkàn rẹ̀ nigba ti o wi pe, “Ẹnyin kò mọ̀ ohun ti yio hù lọla. Kili ẹmí nyin? Ikũku sá ni nyin, ti o hàn nigba diẹ, lẹhinna a si túka lọ” (Jakọbu 4:14).

### Kò si Aye fun Ọlọrun

Jesu pa owe kan fun awọn eniyan nipa ọkunrin ọlọrọ̀ kan ti ilẹ rẹ̀ so èso ọpọlọpọ. O yẹ ki o dupẹ lọwọ Ọlọrun nitori ohun pupọ ti o ni yii: nitori o ti ni ju bi o ti n fẹ fun ara rẹ̀ lọ, o yẹ ki o gbiyanju lati ran awọn alaini lọwọ. Ṣugbọn igba pupọ ni o jẹ pe nigba ti awọn eniyan ba n kó ọrọ̀ jọ fun ara wọn, wọn a gbagbe awọn talaka wọn n lepa kiki bi awọn ṣe le ni pupọ. Ọkunrin ọlọrọ yii pinnu pe bi àká ti oun ni lakoko naa kò ba tobi tó lati gba awọn ohun ọgbin rẹ, oun o wó o palẹ, oun o si kọ́ eyi ti o tobi.

Nigba ti ọkunrin ọlọrọ yii rò pe oun ti de ibi ti o ga jù ninu ogo oun, nigba ti o rò pe oun ko tun ni ṣiṣẹ mọ́ ṣugbọn oun le maa gbadun iyoku ọjọ ayé oun ninu irọra, Ọlọrun ba a sọ̀rọ̀. O ti gbagbe Ọlọrun patapata, ṣugbọn Ọlọrun n wò o. Ki i ṣe pe Ọlọrun rán an leti pe yoo kú ni ọjọ kan, ṣugbọn O rán idajọ ojiji ti o yara kánkán si i. Ọlọrun wi pe, “Li oru yi li a o bère ẹmi rẹ lọwọ rẹ.”

### Erè Ẹlẹṣẹ

Ọlọrun ti fun olukuluku eniyan ni ẹmi, ojuṣe wa si ni lati pese rẹ̀ silẹ fun iye ainipẹkun. Ki ni yoo ṣẹlẹ bi Ọlọrun ba beere ẹmi wa ki a to pese rẹ̀ silẹ fun Ọrun? Jesu wi pe iru ẹni bẹẹ ni a o sọ “sinu òkunkun lode; nibẹ̀ li ẹkún on ipahinkeke yio gbé wà” (Matteu 22:13). O tun wi pe, “Awọn wọnyi ni yio si kọja lọ sinu ìya ainipẹkun; ṣugbọn awọn olõtọ si ìye ainipẹkun” (Matteu 25:46).

### Ojukokoro

Jesu pe ọkunrin ọlọrọ̀ yii ni aṣiwere nitori o ti ni gbogbo anfaani lati wá Ọlọrun, ṣugbọn o ti fẹ lati to iṣura jọ fun ara rẹ to bẹẹ ti o fi ṣe alainaani igbala ọkàn rẹ̀. Nigba miiran awọn eniyan yoo gbà pe awọn kò ṣe ohun ti o tọ́ nitori wọn ṣe alainaani Ọlọrun, wọn a si ṣe ileri lati fi ọkàn wọn fun Ọlọrun ni ọjọ́ kan, ṣugbọn ni akoko naa wọn fẹran ohun ini wọn to bẹẹ gẹẹ ti wọn ko le fi i silẹ, bi yoo ba tilẹ gbà wọn ni igbala ọkàn wọn.

Diẹ ninu awọn ọmọ ogun ti o wà ni iha Guusu Okun Pasifiki ni igbà ogun sọ ọna ti awọn ọdọmọkunrin fi n mu ọ̀bọ. Wọn yoo dá iho si idi àgbọn kan, wọn yoo so o mọ́ nnkan kan ki a má ba le fa a lọ, wọn yoo si mu akara didùn diẹ sinu rẹ̀ gẹgẹ bi ijẹ. Awọn ọbọ yii yoo fi ọwọ́ sinu rẹ̀ lati mu ounjẹ naa, ṣugbọn ọwọ rẹ̀ ti o di akara mu yoo tobi ju eyi ti yoo le fà jade. Dipo ki ọbọ yii fi akara didùn naa silẹ ki o si sá lọ, yoo jọwọ ara rẹ̀ silẹ fun mimú. Bẹẹ gẹgẹ ni Eṣu yoo jere ọkàn ẹni ti o kọ̀ lati fi ohun ini rẹ̀ rubọ fun ifẹ Ọlọrun.

### Ipese Ọlọrun

Igbesi-ayé wa ninu ayé yii ṣe iyebiye ju iṣẹ wa ojoojumọ lọ, iṣẹ ti a n ṣe, ounjẹ ti a jẹ, oorun sisùn, eré ṣiṣe ati ẹ̀kọ́ ti a n kọ́. Awọn ẹlẹṣẹ n lo gbogbo akoko ati ifẹ wọn fun awọn nnkan wọnni, ṣugbọn Jesu ti wi pe Oun mọ ohun ti a ṣe alaini, Oun yoo si pese. Oun ni O dá wa lati ipilẹṣẹ, bi a ba si gbẹkẹle E, ti a si fẹ lati ṣe ifẹ Rẹ̀, dajudaju Oun yoo fun wa ni ohun gbogbo ti a ṣe alaini.

Jesu wi fun awọn eniyan pe ki wọn kiyesi awọn lili igbẹ. Wọn ki i ṣe laalaa nitori ounjẹ tabi bi wọn o ṣe lẹwà, sibẹ " a ko ṣe Sọlomọni pãpã li ọṣọ́ ninu gbogbo ogo rẹ̀ to bi ọkan ninu wọnyi." Iwọ mọ pe Sọlomọni ni ọrọ̀ pupọ, o si le ni ohunkohun ti o ba fẹ. Ṣugbọn a ti ri ninu awọn aṣọ elese aluko daradara ti o n wọ̀, eyi ti o fi hàn pe ọba ni, nigba ti a si fi ẹrọ ti n sọ nnkan kekere di nla (maikroskop) wò o, a le ri i pe àwọ̀ rẹ̀ kò dọ́gba, a kò si hun un jọ̀lọ̀. Ṣugbọn bi a ba mu itanna kan ti a si fi ẹrọ ti n sọ nnkan kekere di nla wò o, yoo lẹwa pupọ paapaa ju igba ti a fi oju lasan wo o lọ. Ọlọrun ni O dá lili, awọ rẹ̀ si pé; ilà ara rẹ̀ ni a si ṣe ti o lẹwa daradara. Ki ni ṣe ti a ni lati ṣe aniyan nipa aṣọ ti a o wọ̀ nigba ti o jẹ pe Baba wa ni Olupilẹṣẹ ohun gbogbo? Jesu wi pe, "Melomelo ni yio wọ̀ nyin li aṣọ, ẹnyin onigbagbọ́ kekere?"

Jesu pe awọn eniyan Rẹ̀ ni "agbo kekere," ti kò lagbara bi o ba fẹ lati maa dá nikan rin; ṣugbọn bi Oluṣọ-agutan nla ba n tọ ọ, agbo naa yoo lọ si "iha omi didakẹ rọ́rọ́" yoo si dubulẹ "ni papa-oko tutù." O jẹ́ didùn inu Rẹ̀ lati fi Ijọba Ọrun fun awọn ọmọ Rẹ̀ bi o ba jẹ pe ibẹ ni iṣura wọn wà.

**Ilé ni Ọrun**

Ọkunrin ọlọrọ kan fẹ kú ni igba kan, ṣugbọn ọdọmọbinrin rẹ̀ kekere kan kò mọ ohun ti ikú jẹ́. Iya rẹ̀ ṣe alaye fun un pe baba rẹ̀ n kọja lọ ni. Ọmọbinrin kekere yii lọ sọdọ baba rẹ̀, o si beere pe, "Baba, njẹ o ni ilé kan ni ilẹ naa nibi ti o gbé n lọ?" Ọkunrin yii ti lo gbogbo igbesi-ayé rẹ̀ lati kó ọrọ̀ jọ, nigba ti akoko rẹ̀ si de ti yoo kú, kò ni ilé ni Ọrun. Ẹ jẹ ki o dá wa loju pe a n to iṣura wa jọ si Ọrun, nigba ti igbesi-ayé wa kukuru yii bá si dopin, ki a ba le ni ilé ti a ti pese silẹ fun wa loke.

## AWỌN IBEERE

1. Ki ni ṣe ti Ọlọrun fi pe ọkunrin ọlọrọ ti o wà ninu ẹkọ wa yii ni aṣiwere?
2. Ki ni nnkan ti a maa n fi igbesi-ayé wa lori ilẹ wé nigba miiran, nipa gígùn akoko?
3. Njẹ o yẹ ki a maa ṣe aniyan nipa ohun ti a o jẹ tabi ti a o wọ̀? Ta ni yoo pese fun wa?
4. Bawo ni ayeraye ti gùn tó?
5. Nibo ni o ti fẹ lo ayeraye?